# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

NO 860 TUESDAY DECEMBER 1, 1964 (2D


## Awọn Janduku Meji Kan Fi Ara Kọrin

Ni ipari ọsẹ ti o kọja ni awọn Janduku ọmọ ẹgbẹ oselu meji kan lọ kolu ọga ile ẹkọ giga ti Ilesha Grammar School Aluf Josiah Akinyemi ti nwọn si bẹrẹ si ni lu Alufa na eyi ti awọn ọlọpa si fi ri awọn Janduku na ko eyi ti Adajọ ile ẹjọ ti ilu Ilesha si ni awọn ọdaran na lọ san ponun marun dinladọje (£125) tabi ki nwọn lọ si ẹwọn ogun osu.

Awọn ọdaran meji na ni Raimi eyi ti Adajọ ile ẹjọ na ni ki o lọ san Ponun marundinlọgbọn tabi ki o lọ si ọgba ẹwọn osu meji eyi ti ọdaran keji Saka ti Adajọ ile ẹjọ na ni ki o lọ fi ọgọrun Ponun (£100) tanran tabi ki o lọ si ẹwọn osu mejidinlogun fun ẹsun na.

Awọn enia ti awọn ọlọpa mu mọ awọn ọdaran na ni ọgbẹni Sunmọla Adan da Yinusa Abiọla ati Mudashiru Atan ni Adajọ ile ẹjọ na si da sile pe ki nwọn ma lọ pẹlu alafia lori ọrọ ti Adajọ ile ẹjọ na si sọ ninu ọrọ rẹ pe awọn enia na ko ni ẹsun kankan tabi ẹjọ lati jẹ niwaju on lori ẹsun ti nwọn fi kan wọn.

# IDIBO APAPỌ HA DI ỌDUN TO MBỌ?

**EKO:- Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa lati ẹnu Olori ẹgbẹ MDF ọkan ninu ẹgbẹ ti o papọ di ẹgbẹ NNA Ọgbẹni James Otobo ni o ti ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe ki awọn enia ilẹ Naijiria to dibo yio to ọjọ kẹsan oṣu kini ọdun to mbọ yi, Ọgbẹni Otobo si fi eyi to oniwe irohin wa leti nigbati o de lati ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria si ilu Eko.**

Ọgbẹni James Otobo tun ṣe alaye pe ki o to di asiko ti Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Alh ji Abubakar to lẹ tu ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka yio di asiko ti gbogbo orukọ awọn enia to lẹtọ lati dibo ni ilẹ Naijiria ba ti wa nilẹ ni yio si lẹ pe igba na ni nwọn yio tu ile igbimọ na ka.

Ọgbẹni Otobo tun ṣe alaye pe ọpọlọpọ awọn nkan to jẹ alebu to jẹ pe o wa ninu orukọ awọn enia to lẹtọ lati dibo ni ilẹ Naijiria ninu eyi to jẹ pe nwọn kọ-kọ lo sita fun awọn enia ilẹ Naijiria lati ri ka.

Ọgbẹni Otobo tun ṣe alaye pe ko si ikanju ninu eto lati tu ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka rara. Ọgbẹni J. Otobo tun se alaye fun oniwe irohin wa pe ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria si wa lori ẹtọ to ba ofin lọ lati wa titi di ọjọ kẹrinla oṣu kini ọdun to mbọ yi. Ṣugbọn to ba jẹ pe ọrọ ti Ọgbẹni Otobo yi si jẹ otitọ ki nwọn to lẹ tu ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria ka yio to ọsẹ kẹtẹ osu ti a bọ si loni yi. Gbogbo orukọ awọn enia to si ni ẹtọ lati dibo ni ilẹ Naijiria lo jẹ pe ko ti pari bayi ati pe nwọn ko ti fun awọn Igbimọ to ndari eto ibo ti ilẹ Naijiria bayi,

Irohin tun fi ye wa pe gbogbo orukọ awọn enia to lẹtọ lati dibo ni iha Ila Orun ati Gusu ilu Eko ni a gbọ pe nwọn ti tẹ wọn wa bayi. Irohin na tun fi ye po orukọ awọn enia ti yio dibo ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni a gbọ pe nwọn ko ti fun awọn Igbimọ ti nda ri eto ibo ni ipinlẹ na bayi.

Irohin na tun fi ye wa pe ki orukọ awọn enia ti o lẹtọ lati dibo ni ilẹ Naijiria to le pari bayi yio to ọsẹ keji oṣu ti a bọ ṣ loni yi ati awọn enia to jẹ pe o si lẹtọ lati dibo ni yio si to ọsẹ keji oṣu yi gẹgẹbi irohin ti a ri gbọ labẹlẹ na lori eto idibo si ile Igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Nnijiria to mbọ yi



Dokita Nnamdi Azikiwe

Ọkan ninu awọn Agbẹnuso ti egbẹ Dẹmọ NNDP tiojẹ ọkan ninuẹgbẹ ti o parapọ di ẹgbẹ NNA tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa ni badan ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu to kọja pe ohun to jẹ gbongbo lori nkan to jẹ akoko ti nwọn yio tu ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọbana ka ni eto lori orukọ awọn enia to ni ẹtọ lati dibo ni ilẹ Naijiria to jẹ pe ko ti pari titi di asiko yi lo si mu idaduro na lọwọ.

Agbẹnuso Tun ẹgbẹ awọn Dẹmọ N. N. D. P. ko sọ akoko kan to jẹ pe nwọn yio tu ile Igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria na ka ati pe o ṣe alaye pe ko si ẹni kankan to le sọ akoko ti nwọn yio tu ile Igbimọ na ka.

Oniwe irohin wa tun se alaye pe Agbẹnuso fun awọn ẹgbẹ Dẹmọ NNDP tun ṣe alaye pe ki ọmọ ẹgbẹ oselu kan to le mọ pe on letọ lati le je pe nwọn yio dibo fun on lasiko idibo to mbọ yi tubi pe ki awọn ẹgbẹ rẹ yan silẹ gẹgẹbi ẹni ti nwọn yio dibo fun ri Agbẹnuso fun ẹgbẹ Dẹmọ NNDP na tun ṣe alaye pe o di akoko ti nwọn ba ri orukọ wọn ninu orukọ awọn to lẹtọ lati dibo ni Oluwa rẹ to mọ pe on lẹtọ lati jẹ pe awọn adibo yio dibo fun on.



Alhaji Abubakar Tafawa Balewa

Irohin tun fi ye wa lati ọwọ oniwe irohin lati Ibadan fi ye wa pe awọn igbimọ ti ndari iṣẹ eto ibo ti nṣiṣẹ kikan kikan bayi lati ri pe nwọn kọ awọn ile to jẹ pe awọn enia ti yio wa lati dibo nibi tabi aye ti nwọn yio ti lọ dibo ati ibi to jẹ pe apoti ibo yio wa eyi ti awọn enia yio lọ ma


WO OJU EWE KẸFA


## Layẹni Ko fi Ẹgbẹ Afẹnifẹre Silẹ

**EKO-: Ni ana ni irohin de ọwọ wa lati ọwọ ọgbẹni A A Layẹni ọkan ninu ọmọ ẹgbe Afenifere to kuna ninu aye ijoko ti nwọn jadu ni iha Ariwa Agbedemeji ilu Eko fun aye ijoko ibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọbe ile Naijiria to mbọ yi ni o ti ṣe alaye pe on ko fi egbe Afenifere sile rara tabi pe on binu kuro ninu egbe na**

Ọgbẹni Layẹni tun ṣe alaye pe on jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe on ko ni ero kankan lọkan lati fi ẹgbẹ na silẹ. Ọgbẹni A. A. Layẹni tun ṣe alaye pe gbogbo irohin to jade lọsẹ to kọja pe on ti kọ iwe si Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹre pe on ti kuro ninu ẹgbẹ na ni ọgbẹni A. A. Layẹni ti ṣe alaye pe iro patapata ni irohin na ati pe on ko fi igba kan kọ iwe si Adele olori ẹgbẹ na.

Ọgbẹni Layẹni ni ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti awọn Igbimọ ti nṣe eto ibo fun aye ijoko ibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ni ko ba eto ofin lọ lẹhin ti ọpọlọpọ iwe ẹsun kotẹmilọrun si de si ọwọ awọn Igbimọ na eyi


Wo Oju Ewe Kẹfa

# Asaju Rere Ni Ọbafẹmi Awolọwọ

**Lati Ọwọ Adio Mosanya**

Awolọwọ Baba Ọlayinka
Awolọwọ Baba Olusẹgun
Ọbafẹmi Baba Olutọla
Ọmọ O'dua Baba 'Tokubọ
Mo ni iwọ ni Olotu rere
T'agba t'ewe jẹri pe
Iwọ ni Olotu rere
Kosi Olotu ti o dabi 'rẹ
Asiko rẹ l'anlowo lọwọ
Igba tirẹ n'la nrijẹ 'rimu
Akoko ti rẹ l'ankọle mọle
Otẹ ti rẹ l'ambimọ lemọ
B'oba ṣe irọ ni mọ pa o
Gbogbo ilu ki e ma ja mi o
Nigbati Awo nkọ ile iwe ọfẹ
Ẹyin ilu, ẹ ko ranti mọ na?
'Gbati Ajẹriku ngbowo koko goke
Ti t'agbe, T'isowo. T'oṣisẹ nṣe yọtọmi
Aforesunise, Afibiṣolore inu yin po na?
Ẹyin Majeni-bọla-osunwọn nkọ?
A nki, a nsa, ẹ l'ẹyin ko mọ ẹni ku
Kaka kilẹ ku, ṣe ilẹ a ṣa ni,
Kaka ka dọbalẹ fun Gambari ka rọju ku.
Iyẹn ni Tọmọ Oduduwa, Iyẹn ni tọmọ ọkọ
Kaka k'e u ma jẹ sese Afi ṣawa dan'i
Iyẹn ni T'alikọra ọmọ ale
T'oranju kankan mọ owo wukuwuka,
T'oda 'le ru d'ọna ru, t'ofobi f'oran
Awolọwọ f'ija F'Ọlọrun ja fọwọ lẹran.
Ọdalẹ wọn iba ṣe ojiṣẹ ẹrun

Awọlọwọ fi wọn silẹ ko woye
Ọdalẹ wọn ibase Dọkita Majẹkagbagbe
Ọbafẹmi fa wọn si kotu Ọlọrun
Awolọwọ oju oro ni leke omi
Baba 'Nkeere, Osibata ni leke odo
Ibi ani ki gbegbe ma gbe Ibẹ ni gbegbe igbe
Ok'aṣai ṣegun ọta o okaṣai ṣẹgun
Ibi a ni ki tẹtẹ ma tẹ ibẹ ni tẹtẹ itẹ
Okaṣai gun awọn irunmi kunna o,
Bi eruku kaṣai gun wọn kunna o
Ibi ani ki duudun ma dun ibẹ ni dundun dun
Okasai bori ọtẹ yio okaṣai bori o
Oju o'ode lode ṣe ihu gbẹgi
Ọkọ Hannah wa gun molu dandan o
T'ori meji kọ teri ẹ i Ọ orun da se fere wo
Igi ti T' lọrun gbin t' dumare Bomi rin
Yio gbile yio tutu m rinmin
Awolọwọ ko binu eru ko binu ọmọ
Awo sọ olupọnju d'olowo
Atun sọ Alakisa dalasọ
Ka dupẹ lọwọ Ọlọrun Olore
Kasi dupẹ lọwọ Odumare Baba wa
T'ofi Ọbafẹmi ta Naijiria lọrẹ
Ṣe nigbati aja nṣe ile
Ọbọ ko bọ okoo
Bi ọta ba nla ilu ibajẹ Ọmọ rẹ ni yio jo
Ka ku Loni ka wi
Abama ku alarari ko tẹtan
Eke apa eke odalẹ apa ọdalẹ
Ẹni ba da ọrẹ lori 'lẹ
Aba 'lẹ lọ
Alabari ṣu abari rẹ
Jẹki nba ọ tọ wo, oyi jona
Ogbe ori ilẹ, oj'eku ọdalẹ Awolọwọ julọ ọdalẹ
O gb'ori ilẹ oj ẹja
Odalẹ Awolọwọ ju ọ lọ ọdalẹ
O gb'ori ilẹ o d'ọrẹ
Jodijẹsọ, Awolọwọ ju ẹ lọ jọdijẹsọ
Dajudaju o d'ọwọ ilẹ ta jọ mu o
Iwọ dokita oni sobia, mo daju pe
Bi aja gbe ẹgbẹrun ọdun laiye

Ẹran ogun ni yio ṣe o
Eke ṣiṣe ni pa eleke
Ilẹ dida ni pa ọdalẹ
Otitọ nikanṣoṣo ni mu ni hewu ori nẹnẹ
Oda 'Famawowa g b a r e
Ni ọjọ onile gogoro, ọkọ ẹbọra,
Ẹlẹsẹ osi meji
Pa'mọ po pẹlu baba iya rẹ
Onirungbọn gẹrẹjẹ, oni ṣango oke ọya
Fi ma owagbare s'ago bi ẹiyẹ
Asẹhinwa, asẹhinbọ, Aiye dorikodo, ilu ko rọ gbọ
Awolọwọ ẹda nlu'lu ibajẹ
Ọba Ọlọrun ko ni jẹ k'odun
Ọbafẹmi, kasai rodo, od'ori igba
Ori rere ni tawo Awolọwọ kasa darugbo dandan



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwo**

Ẹnyin ọmọ karọ jire
Ẹdamuso, egbe'rin iṣẹgun F'Awolọwọ
Okun anu ṣe mi lori rẹ.
Ṣẹṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹṣẹ.
O gb'Ọmọ mi re, Otun gbede
Ṣẹṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹ ṣẹ.
Oduduwa ṣe mi lori re

Ṣẹṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹ ṣẹ
O gb' Awo mi re, otun gbe- de
Ṣẹṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹṣẹ
Onilẹ yi ṣ' Awo lori re
Ṣẹ ṣẹ ni ki ẹ ma yọ f' Awo, ṣẹṣẹ
O m' ọdalẹ Ọrun t' eke subu
Ṣẹ ṣẹ ni ki ẹ ma yọ f' Awo, ṣẹṣẹ
Baba gb' emi leke alakọra

Ṣẹ ṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹ ṣẹ
Ofun mi ni, bo mo li tawọn yọ
Ṣẹ ṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹṣẹ

WO OJU EWE KARUN

# Phillip Afọlayan Gbenle Di Baba ! !



Aworan oke yi ni tiAlagba, Ọlọla, Oloye Phillip Afọlayan Ajiboye Gbenle ati iyawo rẹ Iyaafin Barikisu Ajọkẹ Gbenle, ẹniti o wa ni ọwọ ọtun Oloye na ni Ọgbẹni Bello Gbenle, ti Ọgbẹni Rapheal A. Abikoye si wa lẹgbẹ osi.

Aworan yi jade ni ọjọ iwuye Oloye Gbenle ninu Agbo ile Ifẹlodun ni 25, Igaga Road Surulere laipẹ yi, Ẹo tun ma ri awọn orișirisi aworan miran ti o jade ni ọjọ iwuye na ninu iwe wa, Oye a mọri o,

— AJẸGBORÒ-DAGBA

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ọjọ oni dara fun ọ lati șe eto ọjọ iwaju, ma si șe binu si ẹnikẹni.

PISCES (Feb 19 - March 20) Awọn ohun ti o le ro tẹlẹ ni nwọn ma a yọju si ọ loni, o si ri nkan gba ju ohun ti o lero lọ

ARIES (March 21 - April 19) Șe pẹlẹpẹlẹ pẹlu are șișe loni ki awọn kan o ma ba șe ijamba fun ọ Gbogbo alamu lo dọbalẹ, a ko mọ eyi ti inu nrun

TARUS (April 20 - May 20) Ko si ohun ti ole șe lo ni ju ki o mojuto ișẹ ara rẹ lọ ki o si ma a sọrọ pẹlẹ titi ilẹ yio fi șu

GEMINI (May 21-June 21) Ti o ba lọ si irinajo loni, O șe alabapade awọn ọrẹ ati ojulumọ ti nwọn oșe iranlọwọ

CANCER (June 22 - July 21) O șeșẹ bẹrẹ igbesi aiye titun nisisiyi ma a kiyesi ohun ti o maa șe daada

LEO (July 23 - Aug 22) O le jowu ju, șọra pẹlu ọrọ ẹnu rẹ si sunmọ awọn ọrẹ rẹ loni

VIRGO (Aug 24 - Sept 22) Ifẹ Olufẹ rẹ nfa si ọ bi o ba si ba tage loni o daju pe nkan oșenu re.

LIBRA (Sept. 23 Oct. 23) Mașe ohunkohun ti o ba le' se loni silẹ di ọla. Akoko ko duro de ẹnikan ọjọ nlọ.

SCORPIO (Oct. 24 Nov. 22) Ișẹ pupọ wa fun ọ loni lati șe oju ọjọ si dara fun ọ lati tẹ siwaju.

SAGITTARUS (Nov. 23 Dec. 21) Ara rẹ yio ma a yi lati isalẹ loni șugbọn șọra pẹlu aisan ojiji

CAPRICORN (Dec. 22 Jan. 19) O gbọ irohin ayọ kan loni ki ile to șu, ọjọ oni si dara ki yio si nkan, Ilọsiwaju wa fun ọ lọjọ iwaju.


# Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọ ọkan ẹhin didun ibadi wiwo tabi sisan ẹjẹduu ati tabi aikoto ẹjẹ ara Inu gbigbona nigbakugbo Igba -aiye riro ọmu riro didun arẹ atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ara ẹșẹ ara sisan ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itoju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orișirisi amodi miran ti o ma ayọ wọn lẹnu ni iru nigbakugba pẹlu

(OLOMI IGO NLA NI)
BERE EGBOGI AJỌ WỌN NPENI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba laila ki awọn Orișiriși rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to da awọn agbalagba aiye atijọ mu ati wipe ko si ohun ti ale fi iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti aiperi n yọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio șe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọn eti riro tabi se iwosan iyọnnu apo ile-itọ egbogi oju didun tabi ni ọna-ọfun didun, ati orișirisi omiran pẹlu wọn mbẹ ni șọbu awọn:-

NIGERIA - MEDICINE STORE
4, Tinubu Sqare Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Ọja

ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

# MINOPHOS – TONIC




Aworan ẹgbe yi fi han ọ gbangba bi ẹda enia ti ri aisi "ẸRAN RA" atipe ojulowo tọniki to le șe ișẹ ribiribi ni ẹjẹ ara ișọri ara rinu egungun gẹgẹbi aworan yi to fi han ọ. MINOPHOS Tọniki a ma jẹki ti tun fa si ara papa ti eniaba nru si ogurodo tabi fun wahala ișẹ si e aiko nri orun un daradara to, bẹni o si darajulọ pẹlu bi ara enia ba ngbona nigbakugba tabi lehin aisan tabi amodi bi igbona iba pọnjupọnju tabi ara wiwo enia nigbakugba.

NIBERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos
Phone-: 2287 Naigeria, (Ọja Ita Faji)

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street (Ọja Ita Faji)
Lagos, Nigeria

ATI NI ȘỌBU
IȘẸ-OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN.

# AWE SI OLOTU

## Eyi Ti Jẹ Balewa?

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmomọ lati kesi Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria lati se i b e r e wọnyin lori ipade ti o pe eyi ti o n pẹlu awọn o l o r i ẹgbẹ oṣelu ilẹ Naijiria ṣe eyi ti nwọn fi ṣe adehun lori eto ipolowo ibo to mbọ yi lati le ẹki nwọn ṣe eto ipolowo ibo to mbọ na lai si i j a larin awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu

Eleyi yio dara pupọ lati le pe akiyesi awọn ọlọpa ilẹ Naijiria si eto gẹgẹbi rogbodiyan ko ni fi si tara lasiko ipade ipolowo ibo na gbogbo nkan to nṣelẹ ni ilẹ Naijiria yi paapa julọ ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria to fi jẹ igba gbogbo langbọ pe nwọn npa ara wọn.



Alhaji Abubakar Balewa

Eleyi yio dara bi nwọn ba le tete fi opin si iru iwa jagidijagan to nṣelẹ ni ibinlẹ Ariwa na. Olotu ẹṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Adehọla Jimọh
ILARO.

ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti nkọmọlede lati kesi Alaga ile igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko Alhaji A. F. Masha nipa ọrọ ti a ti nri ka nipa iwa buburu to nṣele ni ibi ti awọn alagbafọ ti nfọ asọ ati lẹba ile igbẹ to wa ni Amutọ eyi to jẹ pe awọn ọmọ to ti kọ ọrọ sẹnu Baba ati Iya wọn.

Awọn ohun to nṣẹlẹ ni Amutọ na ko si ba oju mu rara paapa ni alẹ eyi to jẹ pe iwa ibajẹ ti awọn ọmọ Ọkunrin ati Obinrin ma nhu ni ibi ile igbẹ ati nibi ti awọn to ntun motọ se. Ẹleyi yio si dara bi Alaga Ijọba ibilẹ na ba le tete ṣe eto lati ko awọn Ọlọpa sibi ti a darukọ rẹ yi lati le ma se itọju ibẹ na to ba ti di alẹ ati paapa pe nwọn ko fi awọn enia to nfọ asọ ni ile ifọsọ na silẹ eyi to jẹ pe nwọn ma nja ole nibẹ pẹlu.

mi ni
Michael Iyamu
Eko.

## Itan Shoyinka Nkọ

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ lati ṣe iwadi nipa Itan Oloyinmọmọ ti a ma nri ka ninu iwe Irohin Imọlẹ eyi to jẹ pe o ti pẹ diẹ bayi ti a ti ri itan rẹ ka. Mo ro pe igbagbogbo ni nwọn ma nbere lọwọ ẹnyin Olotu nipa Ọgbẹni wa J. O. Shoyinka ohun to jẹ pe o le fa ti a ko ri itan rẹ ka.

Eleyi yio dun mọ awa to nka iwe Iwe Irohin Imọlẹ bi a ba le tete ri itan Ọgbẹni yi ka lasiko ati pe itan rẹ si kun fun ọgbọn ati oye fun awa to jẹ ọmọ ilẹ Ẹko

Nitori eyi abẹ ọgbẹni Shoyinka ki o jẹ ki a tete ri itan rẹ ka. Tabi on pẹlu Olotu nja ni ko jẹ ki a ri itan rẹ ka rara Olotu ati Alakoso ile iṣẹ Irohin Imọlẹ a si nfẹ alaye diẹ lati ẹnu nyin nipa ọgbẹni wa yi.

Emi ni
Adesina Dauda
Ijẹbu-Ode

## Igbomina Ati Ekiti Ẹ jẹ Ki a Dibo Fun Dada

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ bale fun mi ni aye diẹ lati kesi awọ ọmọ ilẹ Igbomina ati Ekiti to wa ni ilu Eko lori eto idibo to mbọ yi ohun to jẹ pe o wa lọkan mi bayi ni ki a wa silẹ lori ibo to mbọ yi ki o si mọ iru enia to yẹ ki a dibo wa fun lasiko idibo to mbọ yi.

Ohun to jẹ pe awa ọmọ ilẹ Igbomina ati Ekiti le ṣe ti a le ni iyọrisi to dara ni gẹgẹbi a o ṣedibo wa fun Dọkita P. O. A. Dada ẹni to jẹ pe on gan an lo le ṣe eto to tọ ati ey to yẹ fun ilẹ wa ti a ba le dibo fun wọle nitori eyi mo ro gbogbo awọn ọmọ ilẹ Igbomina ati Ekiti lati dibo wa fun Ọlọla wa yi ki a si lọ silẹ lati le lọ dibo wa fun ẹniti yio ṣe iranlọwọ fun wa ati awọn ọmọ wa lọjọ iwaju. Nitorina o di ọwọ nyin bayi o. Olotu ajinde yio ma jẹ o. ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹṣẹ.

Emi ni
Jimọh Adekẹyẹ
Omu Aran.

## Masha Ẹ Ba Wa Mojuto Eyi

Olotu Inu mi yio dun


## Aiye Toto African Healng Home

Bere ogun itaja Ti o daju Ti a ṣe ni Turari pẹlu lọfinda. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko te Afojuba orişirişi arun ati ilọsiwaju
Lẹnu iṣẹpẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ wa

Office
7. Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin

## Bọ Lọwọ Oso Ati Aje

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- meji £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu şişe pẹlu Iwe şan 20/- mejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogba Arun 22/- meji 40-
Turari isẹgun Ajẹ, Oṣo ati awọn aba tẹnijẹ O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/6- pakẹti 2/
Ki şe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọja yi aabo ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ
Fi owo ranşẹ si

J.O. ,HOYINKA
11 Alaba Street
Oduabọrẹ Mushin.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA „DYNAMIREN" TỌNIK

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki Jamanu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹgidan iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi ara ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ko ba şişẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi ubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.

Bere egbogi na ni Şọbu:

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.

# Asiri Ẹgbẹ NPC Igbomina Tu si Ọwọ Ẹgbẹ Ọdọ Ọlọpẹ

**Lati Owo A. K. Sanusi**

Ni ọjọ Thursday ti o kọja ti ṣe 19/11/64, ni Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin ẹniti ayan gẹgẹbi aṣoju ilẹ Igbomina fun Ibo ti o mbọ yi, fi ye gbogbo awọn ọmọ ilẹ Igbomina Eko iru iwa ibaje, aibikita ati iya ara ẹn rọtọ Ẹgbẹ Olomi.



Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin

Inu mi yio dun lati fi to ẹnyin on awe mi leti pe asiko ti to lati tu asiri awọn Ẹgbẹ Eke fun araiye gbọ morope gbogbo nyin ni ọmọ ẹniti yio ba Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin kọju ninu awọn Ẹgbẹ Lagilagi.

Oyẹ ki owa han si yin loju kedere pe awọn ẹgbẹ Olomi ko ni eto rara, Ṣe bi gbogbo nyin lọgmọ ati igba ti ẹgbẹ NPC ti wa, e ha ṣe ti o wa je pe ara awọn kan ti wọn kon ko ara wọn jọ nitori ati fi oṣelu da owo silẹ lasan ni awọn ẹgbẹ na yan lati gbogun ti Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin, nwọn ti sọ eyi di owo patapata ofi di pe wọn naa owo ribiribi ki wọn ba le jẹ ẹniti yio lọ.

Baknna, lari gbọ pe onisowo Nicholas ni awọn ẹgbẹ yi yan, ti o jẹ ọmọ Oro, Iwa ki ọmọ lakeji ma le je awọn Olomi ni odele yi. Njẹ Ọgbẹni Nicholas le i ye ni pe ko si ẹniti ọmọ ive dada ti osi mọ nipa Oṣelu ni ilu Oro mọ afi on ti o jẹ pe owo ṣiṣe ti wọ lokan. Ohun adanu nlanla ni yio jẹ fun ilẹ Igbomina ti a ba le dibo fun ọgbẹni yi nitori pe lọna ekini kole ṣe igbala kankan fun ilẹ Igbomina. ekeji ko ka iwe to eyi ti o le fi sọrọ ni ile Igbomina ṣe emọ pe Oyin o onisowo ko ṣe iṣẹ yi rara. Ijẹ-kujẹ awọn Ẹgbe Lagilagi yi na lofa ti nwọn fi yan ẹniti onṣe owo re jẹ yi Ẹyin ko ha mọ pe inira ati efo ni eyi yio je fun onlati gba iṣẹ yi. Oha yẹ kia gbe jigi iwoju fun afọju bi? Kini o fẹ wo. Tabi kini agewọ yio fi sibi ṣe. O ha wulo bi? Ẹjọwọ ki ẹ maṣe jẹ ki ẹ to dibo fun ẹnikan oyẹ kiẹ ro iru iṣẹ ti o ti ṣe sẹhin nipa oṣelu papa ni ilẹ Igbomina Ẹyin ko ha ri fi pamọ Ohun ti o fa eyi nipe wọn ko fe anfani fun ilẹ Igbomina ati pe o jẹ imọ ọkan won pe ti awọn ba yan omowe ọna ati ṣe jamba yio de. Ẹyin ko mọ iru oye ti Ọgbẹni Dada gba lori iwe kika, Ṣe wọn mọ pe koni gba igb k gba ni wọn ṣe gbe Ọgbẹni ti Ọlanrewaju silẹ Apapọ ni eyi jẹ fun yin Ogbọn ti wọn nda lati fi bo yin loju niyi. Ohun rere wo ni Ọlanrewaju ṣe larin ọdun marun rẹ Division ti gbogbo ọmọ ilẹ Igbomina nile ati loko da owo nlanla fun, kini abọ rẹ Eyi ti o ti kọja ti lọ, kiẹ maṣe jẹki Ọgbẹni Nicholas tun gba tire

Ni Ilẹ Igbomina, eniti ole ṣe anfani fun ile yi. ti osile gbawa bọ lọwọ awọn ti nwọn ti sọ ile Igbomina di ọkọ iroko wọn ni J. S Ọlawọyin.

Ẹnyin ko ha ri iru ija ti oti je nitori ki ole dara fun ile Igbomina pelu ifarada. Ti o ba jẹ pe eniti okan fe ko owo je ni, nje koti ha ye wio jawogege bi Ohun ti oju re ti ri, Ẹnyin



Alhaji Ahmodu Bello

na mọ pe iṣe ọwọ Ọgbeni Ọlawọyin ni titi ọlọda ti ode omu ati ajase lati Ilọrin. Ti eyi koba nse oto, ẹse ti koṣe de Ilu Ọlanrewaju lati Ilorin. Ṣugbon lori aifi Hausa lọrun sile J. S Olarewaju mu i awọ Ọfa, osi gba Ọba Isioye pada si Offa pelu Nipa eto ti awọn Council, eyiti Ọlawọyin fi igba na je aṣoju ni Ilorin, se sile yi ki eto £26. 000 fun Ilu kokan lati fi kọ ọja Ti oba ṣe pe ẹgbẹ ti ose lẹhin ti ẹgbẹ Olomi, eṣe ti nwọn ko fi kọ ọja yi fun awọn ilu kakiri Ọja ti op ija ni ilu Oro awọn ni wọn ko ọja yi fun ara wọn bo si ni owo tiwa fun iru eto bayi ti awọn egbe Olomi ti teri, eyin ko ha mọ iye ti awọn Ọtun Oro na nitori ọja na ni Ilọrin Ti enyin ko ba fe iru ohun ti o ti ṣele si ile Igbomina lati Ọdun karun sehin ti e b si ne losiwaju ile a pẹlu alafia. Ẹgo kan soso ti ẹ le dibo fun ni Ẹgbẹ Action Group adapọ mọ

UPGA Ẹgbe yi nikan ni o le gba ile Igbomina. la lọwọ iya nitọ ti ẹgbe Olomi tinfi nje nyi Oda hi oju ti Ẹebẹ UPGA bati e a ljọ ba ise a ọko se won ni lati pinle riwa gere ase ofe Nẹ eyi ara ẹ Aura dida kiẹ si na awọn e a yio sọrọ lati dibo fun Ogbeni J S Ọlawọyin eniti ayan fun idibo yi fun UPGA ti anfani ati ominira le tẹ ilẹ Igbomina lowọ Bakanna ni isẹ yio wa ti orisirisi ọna owo sise yio wa.

## Lati Oju Ewe Keji

Obara o bodi, idi o mọ 'le wọn
Ṣẹ ṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi, ṣẹṣe
Obara mba kumọ ifa ni ng ma na wọn logo
Ṣẹ ṣẹ ni ki ẹ ma yọ fun mi ṣẹ ṣẹ.
Eke pa obi odi
Ọdalẹ pa tirẹ ma yan
Oniwa rere ni kan ṣoṣo
Lo pa ti re to yan gedegbe
Eke apa eleke
Ilẹ apa ọdalẹ
Edumare ma jẹ k'ori ti a gberu
Je ori ako - lọjọ Igbehin
Ọrọ mi ode hin ibo
Baba akọwato 'ka - lẹhin titu
Wa sile lowo DEMO eti jedijese enia
Ọrọ mi de hin Ibo

# IROHIN IMỌLẸ

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No 260 TUESDAY DECEMBER 1, 1964 2d


## Ọkunrin Onigbo Kan Wẹwọn Ọdun Mẹta

AKURẸ:- Ninu ọsẹ to koja ni Adajọ ile ẹjọ kekere ti ilu Akurẹ ju Ọkunrin onigbo kan ẹni adọrin Ọdun Ọdaran na si Ọmoso eyi ti Agbẹjọro fun ile ẹjọ na sọ pe Ọkunrin Ọdaran na ni oko kan eyi to jẹ pe taba oloro lile kan ti o npe ni Igbo lo gbin sinu Oko rẹ na eyi ti awọn Ọlọpa to ri Ọkunrin Ọdaran na mu ṣe alaye fun Adajọ ile ẹjọ pe gbogbo iye owo Taba oloro na yio si to (£100, 000)

Ọgbẹni kan ti o jẹ oṣiṣẹ ninu oko ti Ọgbẹni Omoso gbin Igbo na si ti o jẹ pe nṣe ni Ọkunrin na nsan owo fun ni Adajọ ile ẹjọ na ju si ẹwọn Ọdun meji fun ẹsun pe o wa lori ilẹ ti ko ba eto ofin mu Ọgbẹni na ni Francis Chukuma ẹni Ọdun mejidinlọgbọn Ninu ọrọ Ọkunrin na fun Adajọ ile ẹjọ na ni o ti ṣe alaye pe on ko mọ nkankannipa oko na ati pe nṣe ni Ọkunrin na gba on gẹgẹbi Oṣiṣẹ ninu oko na ti o si nfun on ni owo iṣẹ ti on ba ṣe.

Ninu ọrọ awọn Ọlọpa fun Adajọ ile ẹjọ na nwon ti ṣe alaye pe awọn Ọdaran meji na si jijọ nge aba Igbo na ninu oko Ọdaran na eyi to fi jẹ pe awon mejeji ni nwọn mu ninu oko na ni ilu kan ti nwọn npe ni Kajola lẹba Ikọle - Ekiti ninu oṣu k ẹsan Ọdun yi Awọn ọkunrin mejejina ni Adajo ile ẹjo na si ju si ẹwọn iṣẹ alaṣe kara

# Ẹgbẹ NNA Lo Ndina Eto Ilọsiwaju Ilẹ Naijiria -Okpara

Ni ipari ọse to koja yi ni Olori egbe Alakuko ati Olotu Ijoba ipinle Ila Orun ile Naijiria Dokita Michael Okpara so nibi eye irin ajo ipolowo ibo re si ile igbimo asofin ti apapo Ijoba ile Naijiria ni ekun Calabar ni o ti ṣe alaye fun oke aimo ye awon enia to wa sibi eye ipade na pe gbogbo ohun to le mu ilosiwaju wa fun ile Naijiria ni awon egbe NNA si ndina re ti nwon ko je ki o wa sile Naijiria

Orun Naijiria si tun rọ awọn enia iha Ariwa si Iwọ Orun Eket lati wa ni ajumọsepo pẹlu ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA lati le ri pe awọn enia ilu na ri eto anfani ati ilọsiwaju gba ti ẹgbẹ ilọsiwaju Naijira UPGA ba ti gba akoso Ijọba ilẹ Naijiria.

Dokita Okpra tun ṣe alaye pe ti ẹgbẹ ilọsiwaju Naijiria UPGA ba le gba akoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria o ni awọn enia ilẹ Naijiria yio si mọ Ijọba ti ẹ g b ẹ UPGA ṣe akoso rẹ yio si gbe ogo ilẹ Naijiria yọ ni Orilẹ ede Africa ati pe gbogbo awọn enia ilẹ Naijiria ni yio ni ẹtọ lati jẹ anfani ti olukuluku ninu Ijọba ti ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria ba ṣe akoso rẹ

Nibi ẹyẹ ipade Ipolowo ibo na ni Dokita Michael Okpara si fi Ọgbẹni J B Johnso han gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju Naijiria ti nwọn yio dibo fun lasiko Idibo si ile Igbimọ aṣofin ti apapọ



Dokita Okpara

Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi

Dokita Okpara si tun rọ awọn enia agbegbe na lati dibo fun J B Johnson o si tun ṣe alaye fun ọkẹ aimọye enia to wa sibi ipade Ipolowo Ibo na pe ohun to jẹ pe o le mu ile Naijiria ni ilọsiwaju ni Ijọba ti ẹgbẹ ilọsiwaju Naijiriria UPGA ṣe akoso re ati pe on na gan an le mu ki eto aye ilẹ Naijiria ni ilọsiwaju dida.

Olotu I j o b a ipnile Ila o r u n Naijiria na tun ṣe alaye pe gegebi Ijọba ẹgbẹ ilosiwaju ile Naij ria UPGA yio ṣe pin awon ohun to le mu eto ilọsiwaju ati idagbasoke ba enia ile Naijiria ni gegebi awon enia agbegbe kan ba ṣe d i b o won fun ẹgbẹ U P G A eyi to je pe nwon yio kọ ẹgbẹ N N A silẹ eyi ti o ṣe alaye pe ko si fe ire mo awon enia ile Naijiria bi ko ṣe pe ti ara wọn nikan ni nwon nja fun

Lehin eyi ni D ọ k i t a Okpara ba fun awon o m o ile eko won.

Ni ọ j ọ na gan ni olori egbe A l a k u k o, Dokita Michael Okpara si fi awon omo egbe ilosiwaju ile Naijiria ti nwon yio dibo fun han gbogbo awon e n i a ti yio dibo ni ekun Calabar eyi ti o je pe awon o m o egbe Alakuko si fi h a n awon enia na.



Alhaji Ahmadu Bello

LATI OJU EWE KINI

to fi jẹ pe nwọn ko fi gba eto ibo ti nwọn fi yan Ọgbẹni Layẹni gẹgebi ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn yio dibo fun ni iha Ariwa Agbedemeji ilu Eko.

Ọgbẹni Layẹni tun ṣe alaye pe o jẹ nkan to ya on lẹnu lati ri pe irohin pe on kuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe de owo awọn oniwe irohin eyi to jẹ pe o fi jade ninu i w e irohin pe on fi ẹgbẹ on silẹ Ọgbẹni Layẹni tun ṣe alaye pe awọn enia to jẹ pe ẹni buburu ni wọn lọ ṣe iṣẹ ibi na si on awọn ti o tun ṣe alaye pe awọn enia ibi na lọ si jẹ pe nwọn hu iru i wa ibajẹ na si on ti nwọn fi ọ pe eto ti nwọn fi yan on ko tọna rara gẹgẹbi ẹni ti nwọn yio dibo fun ni iha Ariwa Agbedemeji ilu Eko.

Ọ g b ẹ n i Layẹmi tun ṣe alaye pe ohun Adele olori ẹgbẹ on mọ ni pe on ko kuro ninu ẹgbẹ A fẹnifẹre ati pe on ko kọ iwe kankan tabi pe ki Adele olori ẹgbẹ na sọ pe on ri ẹ d a iwe ti on fi kuro ninu ẹgbẹ na gba rara

Ọ m o ẹgbẹ Afẹnifere na tun ṣe alaye pe iyalẹnu lo jẹ fun on nigbati on nri ka ninu iwe irohin pe on ti fi ẹgbẹ na silẹ ati pe nigbati, ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹ g bẹ iwadi ọrọ na boya otitọ ni tabi ki iṣe bẹ rara.

Ọgbeni Layeni si ṣe alaye de on si jẹ ọkan ninu awọn ọmọ egbe Afenifere to duro gboingboin lehin egbe na.

## Ọjọ Idibo

Lati Oju Ewe Kini

sọ ibo wọn sinu rẹ.

Oniwe irohin tun ṣe alaye pe awọn igbimọ na ti gbe ile na fun awọn ti yio kọ awọn ile na. Oniwe irohin tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe nwọn ti bẹrẹ si ni kọ awọn ile na ati pe awọn ile ti nwọn yio kọ si ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yio to mẹwa si ogun ile ti nwọn yio kọ bayi.



Oloye Akintọla


Printed And Published by Modupẹ Printing Press, 16 Bamgboṣe Street Lagos Phone 21895
Acting Editor: (Adele Olotu) 'BAYỌ TIAMIYU 26, Omididun Street Lagos (1/12/64)